“Dájúdájú Ọlọhun maa n lọ alabosi lára, titi ti yoo fi mu u ti ko si nii jẹ ki ó bọ

Láti ọdọ Abu Musa- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Òjíṣẹ́ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: “Dájúdájú Ọlọhun maa n lọ alabosi lára, titi ti yoo fi mu u ti ko si nii jẹ ki ó bọ”, o sọ pe: Léyìn náà ni o ka: “{Báyẹn ni ìgbámú Olúwa rẹ. Nígbà tí Ó bá gbá àwọn ìlú alábòsí mú, dájúdájú Ó máa gbá a mú pẹ̀lú ìyà ẹlẹ́ta-eléro t’ó le} [Huud: 102]”
[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n ṣọ wa lara kúrò nibi itẹsiwaju ninu abosi dídá ẹṣẹ ati ṣíṣe ẹbọ, ati ṣíṣe abosi fun awọn èèyàn nibi ẹ̀tọ́ wọn; torí pé Ọlọhun maa n lọ alabosi lára, O si maa n jẹ ki ẹmi rẹ o gùn ti dúkìá rẹ si tun maa pọ̀, ko waa ni kanju fi ìyà jẹ ẹ, ti ko ba wa ronupiwada, O maa mu u ti ko si nii fi i sílẹ̀ fun abosi rẹ ti o pọ. Léyìn naa ni Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- wa ka: {Báyẹn ni ìgbámú Olúwa rẹ. Nígbà tí Ó bá gbá àwọn ìlú alábòsí mú, dájúdájú Ó máa gbá a mú pẹ̀lú ìyà ẹlẹ́ta-eléro t’ó le} [Huud: 102].

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/5811